FUNERE TI O DAJU
Polowo Oja re ninu
Irohin Onigbagbo
Kowe si
OGA APOLOWO OJA
9, Western Ave;
Suru Lere.

COMPLIMENTARY COPY

# Irohin ONIGBAGBO

No. 4 SEPTEMBER 8—14th 1963 KOBO META

J.A. Fagbohun
Organ, Harmonium
Repairer.
Sales & Service
158 Agege Motor
Rd. Atewolara
Mushin.

# ISE IYANU NI MUSHIN

## Woli wo alarun Medogun

**NI ose to koja ninu ile Adura Iyala street, Mushin, Woli Kogberegbe mu awon alaisan medogun larada lesekanna**

Ni agogo mesan abo ojo na; awon enia bi edunrun pejo ni Gospel Team Church, Iyala street Mushin lati josin fun imularada. Ni arin isin na, awon mokarlelogun, obinrin mewa ekun rin mokanla ti ara won ko bo siwaju ijo lati fara han. Ninu won ni ari awon ti ese ndun, inu rirun, ehin riro ati aileto.

Lehin ti awon ijo ti korin woli kogberegbe bere adura, lesekese gbogbo won si ni larada.

Eyi ti o je iyalenu nibe nipe opolopo awon alaisan wonyi ni o ti nyo awon enia n lenu lati opolopo ojo sehin.

Ohun iyalenu keji ninu isin na nipe emi mu ninu awon olujosin na, nwon si iso asotele. Woli Kogberegbe funrare bere iso Iran fun ninu awon towa josin.

Nibere isin na lojo na, enia ara binrin kan ti oti loyun fun bi osu kejila ti ko le bi sugbon ti Woli Kogberegbe ngbadura fun wa pe. Obinrin na ti bimo. Omo na si je omokunrin bi. Omo na si je omokunrin bi Wole Kogberegbe ti so tele.

Awon enia patakipataki lati Eko, Ikeja, Ijebu, ati orisirisi ilu lo wa sibi isin na. Ninu awon ti won wa, mo ri ogunlogo awon omo ijo Anglican, Methodist Aguda ati awon onimale.

Lasale ojo na mo tun losile adura Gospel Team Church, Itire nibiti Woli Kogberegbe ti nse isin lalale ki nto de be awon enia pupo tun ti nduro de Woli Kogberegbe fun adura ati iran.

Iyalenu ni o je fun mi nitoripe pupo ninu iran ti Woli yi soni won bere si ati ojo keji.



Bishopu J.F. Ogunko

## IJO APAPO IBILE AFIRIKA BERE AJODUN

Ajodun idasile ti ekejileladorin Ijo Apapo Ibile Africa (U. N. A.) bere ni ojo Isinmi to koja pelu adura ebe fun idagbasoke ati alafia Ijo, ati ile Naijiria.

Ni agogo merin osan Alakoso gbogbo Ijo na, Bisopu Oguuko se isin igbo wolelori fun awon Alufa merin.

Ninu iwasu re, Archdeacon J. Uranta toka si awon omo ehin ti won fi agbo eran sile, ti won si tele Jesu lairahun.

O la a ye awon Alufa na pe bakanna ni Jesu npe won lati wasu ihinrere, o ro won pe ki nwon mase kuna ninu ise won.

Loni ni won yio se isin kan ni ile Olorun ti Jehovah Shalem l'Eko nibi won yio ti fi Eni owo J. F. Ogunko je oye alabojuto agba (General Superintendent) ni dede agogo mewa aro. Eni Owo A. A. Henry ni yio si wasu nibi isin na.

Wo oju iwe kejo.

## APEJO AWON ODO IJO METHODIST CHURCH TI NIGERIA

NI ojo kokandin logbon osu kejo odun yi ni awon odo gbogbo ti ile ijo Olorin Meth odist ti ile Najirai se gapejo kan ni Abeokuta ibogbo awon odo kakiri le Najiria lo si wa si be yinde na si na si opin ni ojokeji osu yi.



Woli Kogberegbe

## EKUTE ILE YO KAN JE

JINIJINI mu gbogbo awon enia to ngbe ni nomba 4, Kadara Street, Ebute Metta nigbati won ri oku okunrin kan ti oruko re nje Ezekiel Ogunbiyi eni odun merindinlogota ti oku sinu iyara re ni kutukutu owuro ojo keji osu yi.

O ti to ojo meta ti awon ara ile ti nse akiyesi pe won ko ri okunrin na ninu ile laimo pe o ti ku sinu iyara re ni.

Nigbati ara fu awon alabagbe re, nwon sare lo sodo awon Olopa lati lo fi oro na lo won. Nigbati nwon wo inu iyara baba na, won ri pe o ti ku. Lehin ti nwon se ayewo ara re, nwon ri pe ekute ile ti yo oju baba na je, awon era si tun ti je die ninu eti ati ara baba na.

## OJU OKUNRIN

Awon olopa ti gbe oku re lo si ile lakulaku fun ayewo. A gbo pe alaisi na ko ni ebi kan ni Eko.

## Odo nko ile-Iwe Titun

Awon egbe odo Uzebba ti tun ile ti nwon fe fi ko ile iwe giga se. Lokoko oro mi pelu agbaokunrin egbe won, O so pe nkan ti a nfe ni ki a ri mo wipe ile eko giga wa ni ilu wa tabi abule wa, ati wipe nipa ore ofe Olorun nwon ni ireti lati pari kiko re titi di ojo ke ... odun ti o mbo.

Ogoeni na sosiwaju pe Awon Ijoba ipinle iwo Orun ile Naijiria si ti setan lati ran won lowo ninu nkan ti nwon ma fi ko ile na.

# Awon Oniwasu oni

LATI OWO SEXTON

## Anglican Churhes

LAGOS CATHEDRAL
9. a.m very Rev. F. O. Segun
6.30 p.m Rev. J. B. Talabi

ST. DAVIDS
7. 30 a.m. Holy Communion
9. a.m Mattins the Vicar Mr J O. Adeleye
6. 30 p.m Even song the Vicar

ST. JUDES
7:30 a.m Holy Communion
9. a.m Mattins the Vicar
6.30 p.m Evensong the Curate

ALL SAINTS
8 a.m Yoruba Mattins Mr. G. A. Orekoya
9 15 a.m English Mattins Rev. J. F. Akinrele
6.30. p m Evensong Rev. Sope Johnson

## African Churches

JEHOVAH JIREH
Morning Rev. O. Ajediti
Evening Bro. S. O. Oyawoye

SALEM Morning, Evening

## The Churches of the Lord

ELEGBATA
Morning Mrs. A. O. Ajose
Evening President T. Ghollist

SHOMOLU
10 a.m Mary Amokunmosa
6. p.m. Mary Amokunmosa

## Methodist Churches

OLOWOGBOWO 10. a. m. Yoruba 7. p, m. English

OBUN-EKO 10. a. m. Yoruba 7. p. m. Yoruba

FANTI 5. p. m. FANTI

IKOYI 10. a. m. Yoruba 7. p. m. English

IBESE 10. 30. a. m. Yoruba 5. p. m. Yoruba

IPETU 10. 30. a. m. Yoruba 5. p. m. Yoruba

OKO-OMI 10. a. m. Yoruba 5. p. m. Yoruba

OTTA 10. a. m. Yoruba 4. p. m. Yoruba

YABA 8. 30. a. m. English Bro. J. A. Adeyemo. 10. 00. a. m. Yoruba Revd. E. A. O. Idowu, 5. 30. p. m. Yoruba Bro. M. A. Adesoye, 7. 00. p. m. English Revd. E. A. O. Idowu

OSHODI 10. a. m. Yoruba Bro. S. A. Ogundeyi, 6. 30. p. m. Yoruba Bro. E. A. Shodipo

ABULE-IJESHA 10. a. m. Yoruba Bro. B. T. Odesanya. 7. m. Yoruba Bro. ʃ. O. Ojo.

IMEGBON 10. a. m. Yoruba Chief G. O. Adegoriolu, 7. p. m. Yoruba Bro. O. Olukotun

SHOMOLU 9. a. m. Ibo S. A. Fasanu

IJU 10. a. m. Yoruba 4. 30. p. m. Yoruba

ABULE-OJA 10. a. m. Yoruba Sis. P. M. Akinbo

Williams Memorial 8. 30. a. m. English, 10. a. m. Yoruba 7. p. m. English

MUSHIN 10. a. m. Yoruba 5. p. m. Yoruba

APAPA-ELEMU 10. a. m. Bilingual 5. p. m. Bilingual

APAPA AJEROMI 10. a. m. Biilngual 5. p. m. Bilingua

BORNU CRESCENT 10. a.m. English

KIRIRIRI VILLAGE 10. a.m. Bilingual

TINUBU 8. 30. a. m. Yoruba A. A. Oluwole, 10am English Bro S. E. Johnson. 7 p. m. English Minister



Aworan yi ni ti ɴlufa Obirin ti Ijo Katoliki nibi Ipade won ni Ibadau

TINUBU 8.30am Kroo Minister 5pm Kroo S. A. Osinulu 5pm Togo Bro M. Etuk

IKORODU 10 am Bro A. O. Osota 7p. m. Bro W. Dehinsi.

IGBOGBO
10 a.m Bro Oshin
Bro. C. A. Oluwadaini

GBERIGBE
10 a.m Bro A. Aina
4.30 p.m. Do

AGURA
10 a.m. Bro. Orenuga
4.30 p.m. Do

OKE-ELETU
10 a.m. Bro. J. Olatunji
4.30 p.m Do

BAIYEKU
10 a.m Rev. J. A. Funmilayo
4.30 p.m. Do

EWA-ELEPE
10. a.m Bro Elesho
4.30 p.m. Do

EREFUN
10 a.m Bro Akinbiowu
4.30 p.m. Do

## Abeokuta Churches

ST. PETER AKE
9 a.m Rev. E. O Akinboro
6 p.m Rev. M. A. Adeniyi

IPORO AKE
10 a.m Rev. E. O. Folorunso
6. p.m. Evening Song

FIRST BATIST IJAIYE
10 a.m Rev. E A. Agboola
6 p.m. Bro E. A. Sode

ST. JUDES IJEUN
9 a.m Bro E. Olu Oluyomi
5. p.m Bro M. A. Sanyaolu

AFRICAN IGBORE
9 a.m Rev. S. O. Opesusi
7 p.m Mr. F. O. Ekundayo

IKEREKU ANGLICAN
9 a.m Rev E. O Osinowo
7 p.m Evening Songs

ST. JUDE'S IKIJA
9 a.m Mr. S. O Abiodun
6. p.m Mr. E O Ijaduola

OSIELE ANGLICAN
9 a.m Rev E. O. Oduwusi
5 p.m Bro E. O. Odesesan

ILUGUN ORILE ANGLICAN
9. 30 a.m Mr E. O. Oluwunmi 5 p.m. E. O. Adewumi

ST. PETERS AKONKO
10 a.m J. A. Fajebe
5. p.m E. O Feyisitan

ST JOHN LAGOS
9 a.m Mr Moleigh
6. 30 p.m English the Vicar

ST. ANDREWS
9 a.m Mr. Adesina
6. 30 p.m. Rev. Ajayi

HOLY TRINITY LAGOS
9 a.m Dr J A Ademola
6 0 p.m. Hymn Singing

## Archdeacon ilu Benin lo si Canada

Archdeacon ilu Benin Alufa Eni owo S. O Akinuyu fi ibi sile si ilu Canada ni ojo kokanla osu kejo odun 1963.

Ni ojo isinmi, ni ojo o ma fi Benin sile, nwo se isin pataki fun lati od Archdeacon miran.

O gba adura fun alo Olrun lori irinajo gigun re ilu Canada. Awon ijo gb gbo ni o pe si di olo ol rufu lati ki alufa na pe o gba. Alufa Akinuyiyio p da ninu osu kewa odun


## The Lion Signs

Fun Signboard Onidandan Onigi Imu photo duro lori Tabili, Onte, Oruko kiko si ara jigi. Oruko kiko ara Ilekuu tabi be e be

WA SI ODO LION SIGNS

28, AGEGE MOTOR ROAD. Mushin.



Ema ka iw IROHIN ONIGBAGBO Lo so se

# Esin Idakureku Kotona

Lati owo D. B. Babalola

MO ba enia kan ti o sowon pade bi mo ti si Bibeli mi laaro yi, Ninu iwe Isaiah, ori kerinlelogoji, ese ketala de eketadinlogun. Eni na ti mo nwi yi, ara oko kan lasan ni. O ge igi kan, o si fi lara re ya ina, o tun lo lara iyoku lati fi se onje. Nigbati ara re wa gbona tan, ti ikun re si kun o wa sa igi yoku jo, o si ya ere Olorun kan kale. Niwaju eyi ni o duro si ti o si foribale pelu ebe pe "gbami iwo ni Olorun mi.' Isaiah 4:17.

Ara oko yi' gege bi a ti ri ninu iwa re, o dabi alaini oye kan. Iaiseani-ani ti a ba tumo isise re laiye ode oni, aworan okunrin ara oko na dabi ijuwe ipo ti esin wa ni okan enia pupo. A npin asiko wa, eleyi fun ise tabi iwe kika, eleyi fun igbadun, lehin na eyi ti o ku fun adura. Gege bi ero awon miran iru pipin bayi lo tona nitoripe aiye ko ni dun ti a ba yo awon nkan igbadun kuro..

## NIGBATI OWO BA DI LE?

Bawo ni asiko na ti a nfun esin ti ma nkere si nigbagbogbo. O wa di pe iwonba asiko ti o ba ku lehin ti a ba ti te ife aiye lorun ni. Lehin igbati a ba ti lo gbogbo asiko fun ife ti ara, ti o si ti re okan ati agbara wa, a o wa fi iseju die ti o ku fun adura. Lehin gbogbo wahala ose kan, Isin ojo Isinmi yio gba asiko tire yala afe, tabi a ko.

Nigbamiran ewe, a ma nmura fun Isin ojo Isinmi pelu okun ati agbara ti o ba ku lehin aisun ale Satide, gege bi ara oko ti o sa igi yoku jo lati fi ya ere Olorun kan.

## Isesi Wa Si Olorun

Iru ero bayi nipa esin gegebi ohun akanse pataki ti aiye ko tona. Esin ki se kosemani nikan. Isesi pataki ni ti a gbodo ma fi han ni gbogbo aiye wa, ki se ni igbakan. Ko ye ki okunrin ara oko ti a toka si ma se isin re ni igbakan, sugbon oni lati ma se lojojumo ati ni gbogbo ojo.

Isin Kristi je ise igbagbogbo. O je ona igbesi aiye eda, ati ibalo pelu Olorun. O si ngbe emi ise gbogbo, akitiyan ati igbadun aiye re. Ki se afikun ohun ti a nse ni Isin je, sugbon o je ona ti a ngba lati se ohun gbogbo. Nitorina a ko le ya asiko die soto fun Olorun sugbon a gbodo tun igbesi aiye wa se si ona t emi Isin.



Aworau yi ni awon omo egbe Akorin ti awon Sambe Sambe (Salvation Army) nibi isin ita gbangba.

Ko si ohun ti a le yakuro ninu emi Isin, beni ko si ohun tia gbodo mu kuro ninn ibalo wa pelu Olorun eniti ero re ni lati ma dari okrn wa.

### APERE KRISTI

Kristi papa, olupilese esin Kristiani mu esin na kakiri ninu oro, ero ati ise re. O ko won nipa Esin ninu Ile. O si tun gbe kale larin awon ti o ba pade.

Isin Kristi je imole ninu aiye. Imole na ni lati ma tan nigbakugba. Kristi tika arare se pe. "E jeki imole nyin ki o mole niwaju enia ki nwon ki o le ma ri ise rere nyin, ki nwon si ma yin baba nyin ti mbe lorun logo." Mattew 5 : 16.

Laise aniani, a ko le se ise yi ni akoko kansoso. Agbodo ma hu iwa yi titi ojo aiye wa.

### OLUSE

Sibesibe, ki se ese lati da asiko pataki kan ya soto fun isokan pelu Olorun. Lehin ti Kristi ti ran awon enia lo. "O gun ori oke lo lati gbadura." Matthew 14:23.

Sugbon ko dara lori eyi nikan. O nhu iru iwa bayi ni gbogbo aiye re. Eto ni fun awa ti a gbagbo ki a tele apere Kristi nipa jije oluse Isin Kristi titi aiye wa, ki se ni asiko pataki kan lasan, ki a si mo daju pe Esin gbogbo igba ni esin Kristi.

"Gba aiye mi Oluwa,
Mo ya si mimo fun O,
Gba gbogbo akoko mi,
K won kun fun iyin re."

## Orin Wa Oni

### GBA AIYE MI OLUWA

Orin yi wa fun lilo fun orisirisi igba ikore ati igba iya ara eni si mimo, tabi nigba ti a ba nse idupe. Orin na si tun wa fun opolopo ore ti a nri gba lati odo Olorun.

Nigba ti enia ba wa ni irobinuje a tun le lo orin yi lati sunmo Eleda.

Orin tun wa lati yin Oluwa logo fun ise iyanu re lori awa eda.

1 Gba aiye mi, Oluwa,
Ya si mimo fun 'ra Re.
Gba gbogbo akoko mi;
Ki nwon kun fun iyin Re.

2 Gba owo mi, jeki nwon
Ma sise fun ife Re.
Gbe ese mi, K'Osi je
Ki nwon ma sare fun O.

3 Gba ohun mi, jeki nma
Korin f' Oba mi titi.
Gba ete mi, jeki nwon
Ma jise fun O titi.

4 Gba wura, fadaka mi.
Okan nki o da duro
Gba ogbon mi K' O si lo
Gegebi Oba ti fe.

5 Gb' aiya mi, se ni Tire;
Ki o tun je temi mo.
Gba okan mi, Tire n';
Se n'ite igunwa Re.

6 Gba ife mi; Oluwa,
Mo fi gbogbo re fun O.
Gbe emi pa, ki nma je
Tire nikan titi lai.

## Oro Iyanju Oni

IRU igbekele, yi bi awa ni nipa Kristi sodo Olorun; k ise pe awa to fun ara wa lati se iro ohunkohun bi eni pe ti awa tikarawa; sugbon Olorun ni tito wa; eniti o si ti mu wa to bi iranse Majemu Titun ki ise ti oro, bikose ti Emi; nitori oro a ma pani, sugbon Emi a ma soni di aye. Sugbon bi ise iranse ti iku, ti a ti kowe re, ti a si gbe si ara okuta, ba je ologo tobe ti awon omo Israeli ko le tejumo oju Mose, nitori ogo oju re: ogo ti yio di asan: yio ha ti ri ti ise-iranse ti Emi ki yio logo ju? Nitori bi ise-iranse fun idalebi ba je ologo, melomelo ni ise-iranse ti ododo yio rekoja li ogo.

## ADURA

OLODUMARE a ti Olorun aiyeraiye, iwo ti o mura nigbagbogbo lati gbo ju bi awa ti mura lati gbadura, ti o si ima funni ju bi a ti fe ati bi o ti ye wa lo, Tu opolopo anu re si wa lori; ma dari ohun wonni ji wa ti okan wa mberu, ki o si ma fi ohun rere wonni fun wa ti awa awa ko ye lati bere, bikose nitori itoye ati ilaja Jesu Kristi, Omo re Oluwa. Amin.

THE VOLKSWAGEN WIZARD

Bring your Volkwagen Cars for repairs and maintenance

Expert Volkswagen Mechanic Trained under M.&K. is now out for those who cares.

For the best repairs and moderate charges.

Call at

38 Western Avenue Surulere opposite Army Barracks N. B. No other vehicle is allowed here.

# AWON OLUSO AGUTAN OLORUN





Rev Father [illegible]



EBE AKORIN ALADURA SHOMOLU



Eni Owo D. K. ASEKUN ti Lafiaji





[illegible] Owo Idowu ti Yaba



Eni owo julo Abayode Cole, olori ijo Afirika pelu awon Alufa re

Awoŋ... Oke Baba Aladura Agbaye Ibadade.



Awon... Arin meji: Eni owo Akande ti Abeokuta

Aworan inalo Woli Kogbe-rugbe



Alufa Olorin



Aworan oke yi ni ti awon akewe ijo C.M.S. ni Ijebu Remo. Ti arin yi ni Eni owo alaga A. S. Solarin. Ti isale yi ni awon alufa S.I.M.





Eni Owo Oluwole



[illegible] Elukaiye ti Ebute Metta



Bishobu Dimeari



Alufa E.J Jones alaga ijo Methodist tele



Alufa Oyebajo Alias Activity



Eni owo Talabi ti ijo Faji l'Eko



# Alabojuto Jere Iya nla Aje doba

NI igba kan, okunrin kan wa ti oni ako malu ati ketekete. Igba gbogbo ni o ma ngun ketekete yi lati ibi kan si ibi keji ati wipe o feran lati ma mu ako malu lo si oko lati ma sise ni ojo gbogbo.

Olorun fun u ni ona ati ma gbo oro awon eranko nigbati nwon ba nsoro si ara won.

Ni ojo kan, okunrin yi ati iyawo re joko nwon njeun, ni okunrin yi ba gbo ti ako malu nsoro si ketekete wipe "o ngbadun emi ogbeni ketekete nitori oga wa ma ngun e lo lati ibi kan si ibi kan si ibi keji, ise tire niyen ko si ise miran fnn e lati se, o si nje onje ti o dara sugbon o ma nmu emi lo si oko re lati sise lati aro titi di ale, koriko si ni onje mi, se lo ma nfi ese ju koriko na si mi lati je.

Ketekete si dahun pe "Emi o ko e lona ti o ma fi simi fun iba ojo die. Ketekete so fun u wipe ti oga wa ba de ti o ba mu e lo lati lo sise 'ola nigbati o ba de ibe, ki o ko lati lo sise lola, nigbati o ba de ibe, ki o ko lati sise, a si bere si ni lu e, sugbon ki o subu ma se dide, a tun bere si ni lu e, ma se sise titi di ale nigbati o ba pada de lati oko, ti o ba ju koriko si e bi o ti se ma nse, ma je onje na.

Ni ojo keji Ako Malu se nkan ti Ketekete ni ki o se. Nwon o mo pe igbati nwon nsoro okunrin yi gbo nkan ti nwon nso.

Ni ojo keji okunrin na mu Malu lo si oko re bi o ti se nse. Sugbon Malu ko lati sise lati aro titi di ale, nigbati nwon pada de, okunrin yi ju koriko si Malu, sugbon o ko lati je, oga re ri koriko na ni ibe ni ojo keji.

Okunrin na fi Malu na sile, ni o ba Ketekete lo si oko lati lo sise fun u, Ketekete sise ni gbogbo ojo yen, ebi si bere si ni pa a.

Nigbati nwon pada de, Malu bi Ketekete lere bi okunrin ti se se e loko, sugbon ko le so nkankan. Lehin igbati Ketekete jeun tan, o wa si odo Malu o so wipe Ogbeni Malu, me fe so ona miran fun o nitori oga wa ti so wipe ti on ba mu o lo si oko lola ti o ko, on o ta o fun awon alapata ti yi o pa o.

Nigbati okunrin yi gbo oro won o bere si rerin ni iyawo re ba bi lere nkan ti o nmu rerin ni. O ba so fun wipe on gbo nkan ti awon eranko nso si ara won ti on ba si so fun enikan on yio ku. Obinin na tun bere pe ki o so fun on o si gba lati so fun obinrin na. Okunrin na ba lo si ehin ikule ni o tun gbo ti aja nso fun ewure wipe" oga wa ma go lokunrin o ti kole se abojuto ile re ti o ba ge eka igi ni o ba pe iyawo re pe ki owa gbo nkan ti on gbo, o si ti ilekun iyara re o si bere si na iyawo re pe ko gbodo bi on lere iru nkan be mo.

Okunrin na ati awon ebi re ngbe pelu inu didun. Itan yiko wa pe ki a ma ma wadi akara de ibi kangiri.



Alufa Akande Alufa Ijo St. Stephen ti Abeokuta.



Aworan oke yi ni ti Alufa kan nibiti o ti ntowobo iwe igbeyawo


AWON EGBE ODO
PEOPLES' MONITOR

Nke si gbogbo enyin odo lokunrin ati lobinrin lati wa sinu egbe,

Orisirisi anfani ni o wa fun o gege bi omo egbe.

Akowe Egbe
Mr. J. O Adelowo
9 Western Ave.
Suru—Lere


## Ara Isesi ni oju

### O bere Lati Ose tokoja

Ekan tadawa le yi aiye ogoro enia pada;oro ti yio pe titi ni okan enia ko le ti enu jade, sugbon o ni lati wa ninu iwe tite. Iye enia orile ede aiye npo si, a si ri daju pe idagbasoke wa ninu eko imoye (Science), ise owo ati eko miran. Nitorina, o to o si ye ki Ile Olorun dojuko gbogbo nkan yi pelu agbara ati emi inu ki a ma ba di ero ehin.

E le so pe awon alase ti te Bibeli ni, o kere titi, ogorin ede. Beni, sugbon enia melo ninu wa ni o nka Bibeli? Awon pupo fe lati ma ka Iwe Irohin ti Onigbagbo fun itosona.

Bi a ti ri ti imole awon]esin miran ntan,o ye kiawa elesin Kristi yi isesi wa pada ki won ma bo wa mole. Gbogbo wa ko le je oniwasu sugbon ona kansoso ti a le gba lati tan Imole Kristi nipa Iwe tite jade, eyi ti Peoples Monitor duro fun. Nitorina enyin omo iya mi mo gba enikokan yin ni iyanju ati gbogbo Ile Olorun pelu lati se ise ti Kristi ran wa nipa riran Peoples Monitor lowo.

Gbogbo aiye nwa Iwe tite ti Elesin Kristi kikankikan. Awa ti setan lati te won lorun.

# AGBAJOIROHIN GBOGBO

## IKORE AWON OMODE ST. JAMES IDI ORO LARINRIN

IROHIN ko to afojuba ni ile Olorun ti St. James African Church Idi-Oro ni ojo ti awon omode se ikore won ni ojo isimi ti ise ojo kini osu yi. Ikore na si bere ni dede agogo meji abo osan.

Eni owo J. A. Adekujo lo si se isin ikore na. Awon akorin ti ile Olorun na si se asayan orin meji kan ni ede Gesi ati Yoruba. Eyi orin ti won ko lede Yoruba yen si je "Eredi irokeke yi wi fun mi o."

Won si ta oja Basa ikore na ni ojo keji ti won se ikore na pelu ere oloyinmomo kan. Ere na si bere ni dede agogo meje irole, sile meji ni won si fi wole ere na. Won si tun fun awon omobirin mewa toba dara julo ni ebun ofe lati wo ere na laimasan owo kankan rara.

Awon to si je eleto oja Basa na ni Ogbeni E. A. Idumu (Alaga) Ogbeni S.B. Ogun Emmanuel, Samuel A. Afam, Oladipo Adeogun Omidan Mary Akinyemi awon merin yen si je akowe. Awon to tun pelu na ni Ogbeni T. O. Ewuoso, O. Amore, J. Erinoso, J. A. Ogundaro (Olupolowo Oja) Omidan E. Emmannel, Omidan Felicia Aiyedusi, Iya Afin Beatrice Labelu, Iya Afin Elizabeth Okwudika ati Iya Afin Mary Mukoro.

Eni owo E.A.O. Ransford si ni Alufa ile Olorun na. Ikore awon agba yio bere ni ojo keta osu kokanla odun yi ni dede agogo meji abo osan.

## BISOBU BECK WA FUN IBEWO NIGERIA

ENI owo Andrew Beck Bisobu awon Aguda ti fun ibewo orile Najiria.

Gbara bi oko ofurufu ti Bisobu na se sokale ni ebute oko ofurufu ni aburo re to je ogbogi ninu eto eko ni ipinle ila orun Najiria ati eni owo Bisobu J. K. Aggey to je Bisobu fun agbegbe Eko si lo pade re pelu erie ikinikuabo.

Eni owo Bisobu Beck wa fun ipe ti awon Aguda ti orile ede Nijiria pe lati wa fun eto nipa oro eko ati lati le ba won se oludamoran lori ile eko.

Eni owo na si je ogbokangi, Bisobu Beoks yio be gbogbo orile ipinle Najiria wo ki o to pada si ilu oyinbo ni ojo keje osu yi.

## Isin Ope ni Ile Olorun St Mathew

ONIROHIN wa kan fi ye wa pe a se isin Idupe kan ni ijo St Mathew's Cathedral ni ose ti o koja lati dupe fun ore ofe Olorun ni dida ipinle Midwest sile.

Ninu awon enia jankanjankan ti o wa si ibi isin na ni ri enia bi Alakoso D. C. Osadebay, Oba Benin, Akenzua Keji Kesington Momoh, ati opolopo awon ari malelo enia.

Ninu iwasu re, Eni Owo Rotimi so pe ki gbogbo ijo kun fun adura ki nwon si ri pe nwon se ojuse won lati ri pe se ipinle na yori si re[illegible]

## IRANWO IJO OLORUN

NI ilu Eko, Akowe agba fun ajo igbimo Elesin Kristi ti Naijiria, Ogbeni T. A. Adejumobi ti ke se gbogbo awon omo egbe Igbimo na lati dide lese kese si iranlowo, awon ti ekun omi na so di alaini.

Ninu ipe re, Ogbeni Adejumobi, "Awa npe onikaluku ati se itunu fun awon ti omi na se lose". O ro won lati fi ohunkohun ti nwon ba ni papa owo ranse si Akowe Kekere ti Igbimo Elesin Kristi, Alufa Paul Otis Evans.

Ninu ipe miran, ti a gbo lati ori ero redio lose to koja, Dokita G. A. Ademola gba awon omo Naijiria niyanju lati ran awon ti ekun omi so di alaini lowo.

Lehin ti o soro nipa ekun omi ni agbegbe Abeokuta, o se afikun pe, "Aye wa lati seranwo. Kini o fe fi tore? Ohunkohun ti o wu ki Isin [illegible] Iselu wa tabi [illegible] je, gbogbo eya [illegible] se iranwo.



Aworan yi ni ti Sosi Methodist Tinubu tan fe wo laipe yi

## E WO LULE

### SOSI TINUBU METHODIST DARUGBO

AGBO pe awon ijo Methodist yi wo ile isin Methodist ti Tinubu lule ni aipe yio, won yio si ko titun miran dipo re ti iye owo re yio je £60,000.

Sosi Tinubu je nkan ninu awon ile Olorun ti O darugbo ju ni ilu Eko, asi gbo pe eyiti won yio ko dipo re yio je aramonda ti ko ni l'egbe ni ile Afirika.

Ogbeni G. B. A. Coker eniti ojo alaga fi ye wa pe bi ile na yio ti fa kiki to, yio tun ni gareji ti won yio ma ko moto si.

Dipo eyiti sosi eyiti o wa nibe fini tawa ago kan soso, titun yio ni meji, a si gbo pe yio gba to e bewa enia.

Gbara ti won ti gba pe nwon yio ko so[illegible] titun, ni won ti njosi ninu ile eko awon omode ti o wa ni Marina.

A gbo pe won yio wo sosi na lule laipe yi, asi gbo siwaju si pe awon omo ile eko yio ma ba eko won lo ni ibi kan ti a pese fun won ni Holy Cross School.

## Isin Ori Redio

ISIN owuro ti oni yio bere ni agogo meje owuro. A o se isin na ni ede Hausa lati ile Olorun, St. Bartolomeu, Wusare ni ipinle Ariwa.

Awon Ijo Onitebomi (Baptist) ni yio se isin ti agogo mejo abo ale.

Ni agogo mesan abo ale, a o gbo asayan orin lati ile eko giga ti awon Aguda ni St. John's Kaduna. Eniti yio dari eto na ni Alufa Scanlan.

Lopin ojo isimi yi ni agogo mokanla koja ogun iseju (11.20 p.m.) awon oluteitsi ero redio yio gbo isin kukuru kan fun ojo isimi ketalu John Bromp Oratory.

Ni ojobo (Thursday) larin ose ni agogo mesan ku iseju medogun, a o gbo asaro orin ose lati enu Alufa Canon B. A. Adelaja. Ohun ti yio jiroro le lori ni "Ayo."

Ni ojo Jimo, ni agogo mejo abo Dokita Adameda yio soro lori "isoro lona awon omo ehin."

## EKUN OMI SE BEBE: O TU ILE ATI ILU

OFO ati idamu nla de ba awon olugbe adota abule ni agbegbe Abeokuta lenu lolo yi nigbati odo ogun kun bo bebe re mole. Ekun omi na ko se fi enu so. Lojiji ni o ro wo abule ni oru, olukaluku enia si ji lati oju orun lati sa asala fun emi re.

Bi ekun ati ikanu ti gba agbegbe na kan fun ofo ati, ad nu yi, beni awon Elesin Kristi ati egbe alanu miran nwa enia lati se iranlowo fun awon ti idamu ba.

FOUR BROTHERS ENGINEERING WORKSHOP

Fun atunse ti o daju lara Moto Volkswagen re wasi odo

FOUR BROTHERS
31, Agege Moto, Road,
MUSHIN.

